# Àṣọtọ́ àti Àkọtọ́ àwọn Àṣìpa Òwe Láwùjọ Yorùbá

*Azeez, Wasiu Adéwálé*


## Àṣamọ̀

*Ohun tó jẹ́ àfojúsùn iṣẹ́ ìwádìí yìí ní láti ṣe àṣọtọ́ àti àkọtọ́ àṣìpa òwe ní àwùjọ Yorùbá pàápàá jùlọ bí àṣìpa àwọn òwe wọ̀nyí ṣe ń peléke sí. Pépà yìí ni láti ṣe àgbéléwọ̀n ọ̀nà tí àṣìpa àwọn òwe wọ̀nyí ṣe ń wáyé nípa siṣe àlàyé kíkún lórí òwe kọ̀ọ̀kan tí a ṣe àyẹ̀wò wọn. A máa wo bí wọn ṣe ń pa òwe wọ̀nyìí àti ìlànà tó yẹ kí wọ́n máa lò láti gbé òwe náà kalẹ̀ bó ṣe tọ́ àti bó ṣe yẹ. Fún ìfẹ̀sẹ̀múlẹ̀ iṣẹ́ àkànṣe yìí, a ó ṣe àmúlò tíọ́rì ìfojú ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀ wò lítíréṣọ̀. Àyọrísí iṣẹ́ ìwádìí yìí fi hàn pé àìlàkàkún ṣíṣe àmúlò èdè Yorùbá àti kíkọ́ sílẹ̀ ló ṣe okùnfà ipò tí àṣìpa òwe wà láwùjọ Yorùbá. A dábàá ọ̀nà àbáyọ láti lè borí ìṣòro àṣìpa òwe láwùjọ Yorùbá.*


*Kókó ọ̀rọ̀:* *Òwe, Àṣọtọ́, Àṣìpa, Àkọtọ́*

## Ìfáàrà

Bótitọ́ kò sí mọ́, bó ti gbà ló kù ni àwùjọ Yorùbá, ṣùgbọ́n tí a bá ni ká fi wèrè sílẹ̀ kí ó ṣe òkú ìyá rẹ̀ bó ṣe fẹ́, a ó rí wí pé sísun ni yóò sún-un jẹ. Káàkiri àgbáyé ni wọ́n tí ń lò òwe àti wí pé ìran Yorùbá fẹ́ràn láti máa ṣe àmúlò òwe nígbàkúùgbà, èyí ló sì fà á tí a kì í fi ṣe àfẹ́rí òwe nínú àfọ wọn. Ọpọ́ àwọn ọ̀mọ̀ràn ni wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí òwe Yorùbá. Adégbìtẹ́ (2003) ṣiṣẹ́ lórí òwe àti èdè àìyédè tó máa ń farahàn láwùjọ gbajúmọ̀ àwọn olórín Yorùbá. Èyí jẹ́ ìlànà tí àwọn ọ̀kọrin gbajúmọ̀ tí máa ń lo òwe nínú àwọn orin fún ìbáwí tàbí ìkìlọ̀ láàárín ara wọn. Kòṣéémànì (2010) náà sisẹ́ lórí òwe Yorùbá. Fátùrótì (2015) ṣàfihàn ìlò-òwe nínú àsàyàn ewì Adébáyọ̀ Fálétí pàápàá jùlọ bí Fálétí tí máa ń gé òwe kúrú tí yóò fi ìparí òwe náà pamọ́ láì ní sọ ọ́ síta. Ṗápàá jùlọ ọ̀nà tí àwọn Yorùbá máa ń gbà lo òwe bí yíyanjú aáwọ̀, ìbáwí, ìkìlọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bákan náà ni Fájẹ́nyọ̀ àti Adéoyè (2016) ṣiṣẹ́ lórí ipa tí òwe ń kó nínú ìfẹsẹ̀múlẹ̀ ìwà ọmọlúàbí. Wọ́n tọ́ka sí àwọn òwe tó ń tọ́kasí ìbọ̀wọ̀fún, jíjẹ́ olóòótọ́, ìfaraṣiṣẹ́ àánú ṣíṣe àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo àwọn onímọ̀ yìí ni wọn sisẹ́ tó lóòrìn lórí òwe ṣùgbọ́n wọ́n kò mẹ́nuba àsìpa òwe rárá nítorí láwùjọ lóde-òní ọ̀gẹ̀dẹ̀ àsìpa òwe ń bàjẹ́ ẹ̀ ló ń pọ́n. Ọpọ̀ òwe ní wọ́n ti dorí wọn kodò bí àdán tí ìtumọ̀ kò sí fẹ̀sẹ̀rinlẹ̀ mọ́ dáadáa..

Ọgọ̀rọ̀ àṣìpa òwe wọ̀nyí ló ń jẹ jáde lẹ́nu àwọn tí a mọ̀ sí àgbà Yorùbá, èyí sì jẹ́ kí ogunlọ́gọ̀ àwọn ọ̀dọ́ rò pé ohun tó tọ́ ni wọn ń sọ. Bí àgbàlàgbà mìíràn tilẹ̀ fẹ́ sọ̀rọ̀ ní èdè abínibí rẹ̀, ìyọnu ló máa ń jẹ́; dípò pé irúfẹ́ àgbà bẹ́ ẹ̀ á pa òwe bó ṣe tọ́ àti bó ṣe yẹ. Lóòótọ́ lọ́pọ̀ ìgbà ni àwọn akéwìkọ̀tàn máa ń ṣe àjọ̀npọ̀ òwe kí ó bá ní ìtumọ̀ tí wọ́n fẹ́, ṣùgbọ́n síbẹ̀ ọ̀pọ̀ òwe mìíràn wà tó jẹ́ wí pé àsìpa òwe kì

í à mọ̀-ọ́-mọ̀ pa ní atorí kòdì. Àwọn ọ̀kọ̀tàn tí a mọ̀ mọ ìlànà yìí jù ni Adébáyọ̀ Fálétí, Ọládẹ̀jọ Okédìjí àti Kọ́lá Òní, wọ́n fẹ́ràn láti máa ṣe àgbélẹrọ òwe fún lílò tara wọn nìkan. Àsọtọ́ yìí jẹ́ àkọ́kọ́ ohun tó dá wàhálà sílẹ̀ kí á tó wá sọ àkọtọ́. Àsọtọ́ ló bí ìṣòro àkọtọ́, ìdí ni wí pé, bí òǹkàwé bá fẹ́ ka ìwé Yorùbá tí kò ní àkọtọ́ tó mọ́yánlórí irúfẹ́ ẹni bẹ́ ẹ̀ a fi adéògún pe adéogun, èyí ló sì pọ̀jù nínú ohun tó ń ṣe akóbá fún àṣìpa òwe. Bí èyí bá wá rí bẹ́ẹ̀, tíọ́rì tí á ṣe àmúlò fún iṣẹ́ ìwádìí jẹ́ tíọ́rì ìfojú ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀, tí ó jẹ́ ajólórí àwùjọ tí a bá sì wo bí àṣìpa òwe wọ̀nyí ṣe ń wáyé kò sẹ̀yìn àwùjọ tí wọn ti ń ṣe àmúlò rẹ̀. Fún ìdí èyí, àwùjọ náà ni yóò tọ́ka ìlànà tí a fẹ́ fi dẹ́kun àsìkọ àti àṣìpa òwe láwùjọ Yorùbá. Nítorí náà, tíọ́rì yìí a ṣe ìrànwọ́ fún àti rí ọ̀nà àbáyọ nípa ìbáṣepọ̀ àwùjọ.

## Tíọ́rì Àmúlò

Tíọ́rì tí a yàn láàyò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí ni tíọ́rì ìfojú ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀ láwùjọ, tíọ́rì yìí kan náà ni a tún mọ̀ sí sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí èrò Adéyẹmí (2006:31); ó gbà pé ìmọ̀ nípa ìbárẹ́pọ̀ tó wà láàárín lítíréṣọ̀ àti àwùjọ ní ó jẹ́.(Ọpẹ́fèyítìmí, 2011:42) wí pé ìgbàgbọ́ àwọn ọ̀mọ̀ràn lórí tíọ́rì yìí ni pé èso àwùjọ lítíréṣọ̀ jẹ́.

Taine ọmọ ilẹ̀ Faranse tó jẹ́ agbátẹrù tíọ́rì yìí fihàn pé àfojúsùn tíọ́rì ni wíwo bí àwọn ohun kan ṣe ń yípadà láwùjọ nípa ìròrí àti ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwùjọ mìíràn. Fún ìdí èyí àwọn onímọ̀ sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ máa ń ṣe àyẹ̀wò iṣẹ́ ọnà aláwomọ́ lítíréṣọ̀ lọ́nàkọnà. Wọn á wo iṣẹ́ ọ̀nà gẹ́gẹ́ bí èso àwùjọ àti ọ̀nà tí wọ́n gbà sẹ̀dá irúfẹ́ iṣẹ́ ọnà bẹ́ẹ̀. Ìdí ni wí pé, ibi tó bá wu àwọn onímọ̀ sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ni wọn ń gbà ṣe ìtọpinpin iṣẹ́ ọnà, ó lè jẹ́ ṣíṣe àtúpalẹ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀ àti èrò báyéserí ohun ìdàgbàsókè tó dé bá iṣẹ́-ọnà láwùjọ (Adéyẹmí 2006:31). Nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí, pàtàkì àfojúsùn tíọ́rì yìí ni bí òwe ṣe ṣe kókó àti ìlànà ìyípadà tó ń bá àwọn òwe nípa àṣìpa wọn látàrí àkọtọ́ àti àsọtọ́ láwùjọ Yorùbá.

## Ìṣàmúlò Ìjúbà Ṣíwájú Òwe Láwùjọ Yorùbá

Òwe lẹsin ọ̀rọ̀, ọ̀rọ̀ lẹsin òwe, bí ọ̀rọ̀ bá sọnù, òwe lá fí ń wa. Ajíbọ́lá (1979) Kòṣéémànìí (2010) Adéoyè àti Fájẹ́nyọ̀ (2016) ni wọ́n ṣàlàyé nípa ṣíṣe àmúlò òwe ní àwùjọ Yorùbá. Ẹnu àwọn àgbà ni a ti máa ń gbọ́ òwe, a kì í fi òwe sí ẹnu ọmọdé. Ìdí ni wí pé ìrírí àti òye ni àwọn àgbà ń lò láti tẹ́ òwe bí à ń tẹ́ní nínú àfọ̀ wọn láwùjọ. Bóyá nígbà tí wọ́n bá fẹ́ pe àkíyèsí nípa ìmọ̀ràn, ìbáwí, ìtọ́sọ́nà yíyan jú aáwọ̀ àti fífi ìrírí hàn láwùjọ.

Ọmọdé kì í sọ̀rọ̀ tàbí p'òwe láì sọ àwọn ọ̀rọ̀ ìtẹríba láti lè fi júbà àwọn àgbà tó wà ní ìkàlẹ̀ nígbà tó fẹ́ p'òwe. Èyí ni pé ó di dandan kí ọmọdé gbàṣẹ lọ́wọ́ àwọn àgbàlagbà kí ó tó pa òwe. (Fájẹ́nyọ̀ 2008:29). Ìdi ni pé bọmọdé bá láṣọ bí àgbà, kò lè lákìsà bí àgbà ní wọ́n fi máa ń lo irúfẹ́ àwọn ìpèdè bá wọnyìí sáájú: "Ẹ̀yìn àgbàlagbà lẹ máa ń sọ pé" Ìtumọ̀ rẹ̀ ni pé àgbàlagbà kì í tan lórílẹ̀ kò sí bí àwọn àgbàlagbà ṣe lè kó ara wọn jọ tó, bó ṣe ọdún àti ìrí kọ̀ọ̀kan wọn á fi jura wọn lọ.

”Àwọn baba wa ni wọ́n máa ń sọ wí pé” Ìyẹn ni wí pé ọ̀rọ̀ ọlọ́gbọ́n pẹ̀lú ìrírí lẹ́nu àwọn àgbà ló fi máa ń jẹ́ pé, bí ọmọdé bá tilẹ̀ mọwọ́ wẹ̀ tó bágbà jẹun, ó gbọ́dọ̀ gbàṣẹ. “Kí òwe yìí jẹ́ tí ẹ̀yìn àgbà o“ Bí ọmọdé bá gbàgbé tàbí tí ọkàn rẹ̀ fò ó láti júbà síwájú, lẹ́yìn tí ó bá ti pa òwe tán. Ó lè ṣe àtúṣe nípa sísọ irúfẹ́ gbólóhùn òkè yìí. ”Tótó, ó ṣe bí òwe o!” Ìpè àkíyèsí ni gbólóhùn òkè yìí jẹ́ fún ọmọdé láti fihàn níwájú àwọn àgbà pé òun júbà wọn kí ó tó p'òwe. “N kò tó òwe pa níwájú ẹ̀yìn àgbà o!” Fífi ìwà ìrẹ̀lẹ̀ hàn lórí ìmọ̀ tí ẹni tí ó fẹ́ pa òwe níwájú àwọn àgbà ni èyí jẹ́. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni wí pé ìrírí ní àgbà, ìrírí yìí ló sì jẹ́ atọ́kùn fún ìṣẹ̀dá òwe. Yorùbá gbà wí pé tí awo bá kì fún ni, a`á kì fún awo padà ni. Gbogbo ìpèdè gbígbàṣẹ lọ́wọ́ àwọn àgbà wọ̀nyí náà ní ìdáhùn sí láti ẹnu àwọn àgbàlagbà tó mòye. Wọn á fèsì padà pé: “Wà á rí òmíràn pa” “Làákàyè rẹ̀ kò ní kú” “Wà á pa òmíràn” “Ìmọ̀ rẹ kò ní jọ́bà” Ìṣàmúlò òwe gbọgbọ́n púpọ̀, nítorí bí ọ̀rọ̀ bá ṣe rí ló máa ń ṣe okùnfà irúfẹ́ òwe tí ènìyàn fẹ́ pa ní àkókò tí ọ̀rọ̀ náà ń lọ lọ́wọ́.

### Àtúnṣe Àṣìpa Òwe nípa Àṣọtọ́ àti Àkọtọ́

Òwe kì í ṣe àjòjì láwùjọ àwọn Yorùbá nítorí nínú ìṣe ojoojúmọ́ wọn ni òwe tí má ń farahàn, bóyá ni ti àdáṣe tàbí àjùmọṣe àwùjọ wọn. Bí o tilẹ̀ jẹ́ wí pé ọ̀kẹ́ àìmọye àwọn ọ̀mọ̀ràn ló ti ṣiṣẹ́ púpọ̀ lórí òwe Yorùbá. Ohun tó jẹ àwa lógún nínú iṣẹ́ yìí ni àtúnṣe àṣìpa àwọn òwe Yorùbá bóyá nínú afọ̀ ojoojúmọ́ tàbí kíkọ sílẹ̀, èyí tí ó ń ṣe àkóbá fún ìlo òwe gẹ́gẹ́ bí ó ṣe yẹ kí a lò ó.

Àṣìpa òwe: Ọgá tà, ọ̀gá ò tà, owó aláàbárù á pé.

Àsọtọ́ àti àkọtọ́: Ọgọ́ tà, Ọgọ́ ò tà, owó aláàbárù á pé.

Ọgá kọ́ ni Yorùbá ń pè é, Ọgọ́ ni. Ọgọ́ jẹ́ àwọn ìdọ̀tí tí a gbá jọ, ó lè jẹ́ okùn tí kò wúlò, tákádá, aṣọ, ẹ̀fẹ́kù, àwo, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nígbà tí a bá gbá àwọn ìdọ̀tí wọ̀nyí jọ tán tí fẹ́ lọ dàá nù, a tà á o, a kò tà á o, aláàárù tí a bá gbé e fún kí ó bá wa dàánù ní láti gba owó iṣẹ́ rẹ̀. Wọ́n máa ń lò òwe yìí nígbà tí ènìyàn bá ti mọ̀ wí pé àdéhùn ṣísan owó tàbí nǹkan mìíràn wà láàrin wọn.

Àṣìpa òwe: Ìtì ọ̀gẹ̀dẹ̀ ni kò tó ohun tí à ń yọ àdá sí.

Àsọtọ́ àti àkọtọ́: Ìtì ọ̀gẹ̀dẹ̀ ni kò tó ohun tí à ń lọ àdá sí.

Lílọ àdá lórí ọlọ túmọ̀ sí pípọ́n àdá èyí ni wí pé à kó lè fi agada ọwọ́ bẹ ìtì ọ̀gẹ̀dẹ̀ láìjẹ́ wí pé a lo àdá, ṣùgbọ́n kò pọndandan kí a pọ́n àdá kí a tó fi bẹ́ ìtì ọ̀gẹ̀dẹ̀, nítorí pé ìtì ọ̀gẹ̀dẹ̀ jẹ́ ẹ̀yà igi kan tí kò ní ẹ̀mí nínú àti wí pé omi pọ̀ ní ara rẹ̀, èyí kò jẹ́ kí ó sòro fún ni láti gé. Bí a pọ́n àdá, bí a kò pọ́n àdá tí a bá ti gé ìtì ọ̀gẹ̀dẹ̀ yóò gé. Wọn máa ń ṣe àmúlò, irúfẹ́ òwe yìí nígbà tí ènìyàn bá ń páyà lórí nǹkan tí kò níra rárá.

Àṣìpa òwe: Danwò ló bí ìyá ọ̀kẹ́rẹ́.

Àsọtọ́ àti àkọtọ́: Danwò ló bí ìyà ọ̀kẹ́rẹ́.

Ìtàkùn ni ọ̀kẹ́rẹ̀ máa ń fi ń ṣe agbára láti bọ́ sí orí igi kan sí èkejì pàápàá lórí igi ọ̀pẹ tó bạ súnmọ́ ara wọn. Tí ìtàkùn bá já, ọ̀kẹ́rẹ́ kò lé fò tàbí bọ́ sórí igi kan sí èkejì, èyí niwọ́n fi máa ń pwe pé ìbí tàkùn ò bá já, ọwọ́ ò le b'ọ̀kẹ́rẹ́. Tí ọ̀kẹ́rẹ́ bá fẹ́ dán fífò wò láì sí ìtàkùn, ìyà ló máa fi ń jẹ ọ̀kẹ́rẹ́, ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń p'òwe yìí. Òwe yìí jẹ́ òwe ìkìlọ̀ nítorí pé tí ènìyàn kan bá lọ ṣe ohun tí agbára rẹ kò le ká, ìyà ni yóò bá níbẹ̀.

Àṣìpa òwe: Lówelówe làá lu ìlù àgídìgbo.

Àsọtọ́ àti àkọtọ́: Lówelówe làá lu ìlù ògìdìgbó.

Àpótí tí wọn tó òjí-àgbá kéékèèké sí ojú ìhò tí gbẹ́ sí ààrin àpótí yìí tí wọ́n ń ta láti gbé ohùn orin jáde ni à ń pè ni àgídìgbo. Ìlù tí wọn máa ń lù ní ilédì awo ni ògìdìgbò. Ìlú yìí máa ń ṣe pìrìmù mọ́lẹ̀ bí ẹsẹ̀ Ìmàdò wọn á sì ya àwòrán sí ara rẹ̀. Ilé awo ní wọn tí máa ń lu ìlú yìí, ó sì nídìí tí wọ́n fi ń lùú. Wọ́n máa ń ṣe àmúlò irúfẹ́ òwe yìí nígbà tí wọ́n bá ń ṣe ìkìlọ̀ fún èèyàn lórí iṣẹ́ kan tí ó le dá wàhálà síni lagbada.

Àṣìpa òwe: Ọkẹ̀rẹ́ g'orí Ìródò, ojú ọdẹ dá.

Àsọtọ́ àti àkọtọ́: Ọkẹ́rẹ́ g'orí Ìrókò, ojú ọdẹ dá.

Ohun tí ó bá jọ ohun lá fi ń we'un, Ìròdò ni kí wọ́n dẹ àwọ̀n, tàbí ajẹ̀ sínú odò nítorí a tí mú àwọn ẹran inú omi. Kàkà kí ẹja kó sínú rẹ̀ tí ó bá dúró sórí Ìròdò yìí tí a mọ̀ sí páńpẹ́ kò lè mu ẹja náà; Ìrókò jẹ́ igi abàmì tí ó sì máa ń ga fíofío, tí ọ̀kẹ́rẹ́ bá gorí ìrókò, kò sí bí ọdẹ ṣe lè yinbọn tó kò lè ba ọ̀kẹ́rẹ́, bákan náà ni igi ìrókò kò ṣè é kù fìrì gùn. Ìbáwí ni wọ́n máa ń lo òwe yìí fún nígbà tí ènìyàn ba tí kùnà lórí nǹkan kan tí kò ní àtúnṣe.

Àṣìpa òwe: Ohun tí ń bẹ lẹ́yìn Ọfà, ó ju òjé lọ. (Ohun tí ń bẹ́ lẹ́yìn Ẹ̀fà, ó jú èje lọ.)

Àsọtọ́ àti àkọtọ́: Ohun tó ń bẹ lẹ́yìn Ọfà, ó ju òjé lọ.

Ọfà ara jẹ́ ìlú kan ní Ìpínlẹ̀ Kúárà, bákan náà ní Òjé jẹ́ ìlú kan tí a kò gbọ́ mọ́ nílẹ̀ Yorùbá, èyí ni wí pé ìlú yìí tí wà rí. Òǹkà ni ẹ̀fà àti èje jẹ́ nínú òǹkà Yorùbá. Àwọn tó ń ṣe àṣìpa òwe yìí gbà pé ìlú tó ń bẹ lẹ́yìn Ọfà ju Òjé lọ, tàbí ohun tó ń bẹ lẹ́yìn ẹ̀fà ó ju méje lọ. Kò rí bẹ́ẹ̀ rárá. Ọfà jẹ́ fífi ẹni dógò láti ya owó nílé ọlọ́lá, iye owó tí wọ́n báyá ni ẹni tí wọ́n bá fi dógò yóò fi sin ọlọ́lá yìí. Bí wọ́n bá yá ọ̀kẹ́ mẹ́fà, ó fihàn pé odidi ọdún mẹ́fà ni ẹni yìí yóò lò nílé olówó. Irúfẹ́ ẹni yìí gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí ó lágbára iṣẹ́ àwọn ni wọ́n máa ń pè ní 'Ìwọ̀fà'. Èyí yàtọ̀ sí ẹ̀rú nítorí pé tí ó bá ti singbà pé iye ọdún tí wọ́n dá irúfẹ́ ìwọ̀fà bẹ́ ẹ̀ yóò gba òmìnira, ṣùgbọ́n ẹrú kì

í gba òmìnira àyàfi tí ọlọ́lá bá ràwọ́n lọ́wọ́ àwọn olówó wọn láti sọ wọn d'ọmọ ló kù. Nígbà tí ìwọ̀fà yìí bá ń singbà, a máa mọ oríṣìíríṣìí àwọn ènìyàn ńlá ńlá nítorí kò sí iṣẹ́ tí wọ́n kì í rán-an. Yorùbá bọ̀ wọ́n ní 'ọmọ ọlọ́mọ là á rán níṣẹ́ dé tòrutòru'. Níbi tí wọ́n tí ń ran níṣẹ́ yìí, ní yóò tí mọ àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ láwùjọ, nígbà tí ó bá wá parí Ọ̀fà rẹ̀, gbogbo àwọn tó mọ̀ yìí ní yóò ṣe é lóore, ìyẹn ni wí pé ó jú òjé lọ.

Òjé jẹ́ ohun àlùmọ́ọ́nì tí àwọn Yorùbá kà kún pé ó níye lórí tí wọ́n bá sì fún ènìyàn ní ọ̀fẹ́, irúfẹ́ ẹni bẹ́ ẹ̀ á jẹ́ ẹni iyì láwùjọ, ṣùgbọ́n ohun tó wà lẹ́yìn siṣẹ́ Ọ̀fà, yìí ju òjé lásán lọ. Wọ́n máa ń lo òwe yìí fún ìmọ̀ràn nípa ṣíṣe àforítì.

| | |
|---|---|
| Àṣìpa òwe: | Ẹ̀bìtì ò p'eèrà, ibi ọ̀pẹ́lómọ |
| Àsọtọ́ àti àkọtọ́: | Bí ẹ̀bìtì ò p'eèrà, a fẹyìn fẹ́lẹ́yìn. |

Ẹ̀bìtì jẹ́ ọ̀kan lára oríṣìí ìlànà tí a fí ń mú ẹranko ní ilẹ̀ Yorùbá bí àti ṣe ni pàkúté, ẹ̀bitìtì jẹ́ ókútá ńlá tí a fi okùn àti ọ̀pá dẹ sílẹ̀, kí ó lè mú òkété tàbí àwọn ẹranko tó farajọ ọ́ bí ẹmọ́, màlá, àǹgó, ẹ̀dá, olòsè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Tí a bá wá dẹ ẹ̀bìtì yìí tí kò bá pa nǹkankan dandan ní kí a bá ẹyìn tí a fi sábẹ́ rẹ̀. Ẹyìn jẹ́ èso kan tí a máa ń rí lára ọ̀pẹ, èyí tí a máa ń rí epo, èkùrọ́, eésan àti àdí ẹ̀yan lára rẹ̀. Òwe yìí máa ń wáyé nígbà tí a bó rò pé nǹkan máa ṣe ṣùgbọ́n tí kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́.

| | |
|---|---|
| Àṣìpa òwe: | Bí Ọlọ́run bá pàáyàn lórí yóò fi irun àgbọ̀n di. |
| Àsọtọ́ àti àkọtọ́: | Bí Ọlọ́run bá pàáyàn lórí yóò fi irun àyà di. |

Irungbọ̀ jẹ́ ẹ̀bùn láti ọwọ́ Olódùmarè bí o tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn onímọ̀ ṣáyénsì gbà pé ṣíṣe àfẹ́kù èròjà kan lára máa ń fa kí obìnrin ní irugbọ̀n, bí o tilẹ̀ wí pé nílẹ̀ Adúláwọ̀ bí obìnrin bá hunrùngbọ̀n, ojú òdì ni wọn fi máa ń wo irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀. Bí o tí mọ ni yóò mọ ọkùnrin máa ń ní àdámọ́ irugbọ̀n, ṣùgbọ́n Yorùbá gbàgbọ́ wí pé bí ènìyàn bá párí, èyí ni wí pé kò sí irun níwájú orí ènìyàn tàbí ní ààrin orí.

Ẹ̀wẹ̀, irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ máa ń ní irun àyà. Òwe yìí máa ń wáyé nígbà tí ènìyàn bá ṣe àfẹ́ku, ẹ̀bùn kan, ṣùgbọ́n tí ó wà ni oore-ọ̀fẹ́ ẹ̀bùn mìíràn. Ìtumọ̀ èyí ni wí pé wọ́n máa fi ń gba ènìyàn nímọ̀ràn láti ní ìrètí ògo pé kì í ṣe ẹni àkọ̀tì láwùjọ.

Sòkòtò jẹ́ ọ̀kan lára àwọn aṣọ Yorùbá tí ó máa ń buyì kún ẹwà aṣọ àti ara. Ṣùgbọ́n sòkòtò pé oríṣìíríṣìí bí á ṣe ní ọ̀sọ́rọ́, Kẹ̀mbẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ lọ. Bí Onípàá bá fẹ́ rán sòkòtò á fi àyè ìpá sílẹ̀ lábẹ́, èyí ní wọ́n fi máa ń sọ wí pé ara ẹ̀ lara ẹ̀ sòkòtò onípàá kìí ṣe Ọlọ́pàá. Àṣìpè ọ̀rọ̀ ní wọ́n fi ń pe Onípàá ní Ọlọ́pàá.

| | |
|---|---|
| Àṣìpa òwe: | Ara ẹ̀ lára ẹ̀ sòkòtò Ọlọ́pàá |
| Àsọtọ́ àti àkọtọ́: | Ara ẹ̀ lára ẹ̀ Sòkòtò Onípàá |
| Àṣìpa òwe: | Kí lo rí l'ọ̀bẹ̀ tó fi wárú sọ́wọ́. |
| Àsọtọ́ àti àkọtọ́: | Kí lo rí l'ọ̀bẹ̀ tó fi waro ọwọ́. |

Irú jẹ́ ọ̀kan lára àwọn èròjà amọ́bẹ̀dùn àti wí pé àwọn àgbà gbà pé iṣẹ́ pàtàkì ni irú ń ṣe ní àgọ́ ara tí ènìyàn bá ń jẹ é. Láyé àtijọ́ kò sí bí àwọn obìnrin ìgbà náà yóò ṣe dáná ọbẹ̀ bí ẹ̀fọ́n, ilá, ewédú, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, tí wọn kò ni fi irú sọ́bẹ̀. Bí o tilẹ̀ jẹ̀ wí pé wọ́n ń lo irú náà láyé òde òní ṣùgbọ́n kò fi bẹ́ẹ̀ dàbí alárà. Kí èèyàn waro ọwọ́ túmọ̀ sí wí pé kí ènìyàn ka ọwọ́ tí o fi bu òkèlè oúnjẹ tí ó wà fẹ́ run ọbẹ̀ tó wà káwọ́ kò, ó nídìí kan tó ṣe kókó ló ṣe káwọ́ ro.

Òwe tó jẹmọ́ ìbáwí, nígbà tí ènìyàn bá ṣe nǹkan kan tó kù díẹ̀ káàtó; wọn máa ń pa òwe yìí láti fi sọ fún irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ pé kí ní èrò rẹ̀ tó fi hu ìwà tó hù.

| | |
|---|---|
| Àṣìpa òwe: | Ìdúró ò sí, ìbẹ̀rẹ̀ ò sí fún ẹni tó gbódò mì. |
| Àsọtọ́ àti àkọtọ́: | Ìdúró ò sí, ìbẹ̀rẹ̀ ò sí f'ẹ́ni tó gbódò rù. |

Odó ni a fí ń gún iyán, odó a máa wúwo nítorí ìdí èyí kì í ṣe ohun tí ènìyàn lè gbémì rárá. Ṣùgbọ́n a lè gbé e rù. Wàhálà ńlá ni ń bẹ nínú kí ènìyàn gbódó rù, ó sì sòro kí ènìyàn gbódó rù tán kí o máa ṣe bí ó ṣe wù ú. Akọ iṣẹ́ ni èyí jẹ́ nítorí ń ṣe ni gbogbo ara irúfẹ́ ènìyàn tó gbódó rù a máa gbọ̀n pẹ̀pẹ̀ bí ìdí àpẹ́.

Wọn máa ń pa òwe yìí fún ẹni tí ó bá fọwọ́ ara rẹ̀ fa wàhálà, tí ogun ayé wá ń jàá lọ́tùn-ún lósì ó sì lè jẹ́ ọ̀nà mìíràn tí ó tún dára ṣùgbọ́n ohun tí à ń sọ ni pé kí ẹni tí wọ́n bá pa òwe náà fún máa fi ọ̀rọ̀ rẹ̀ falẹ̀ rárá.

| | |
|---|---|
| Àṣìpa òwe: | Oyè tí kan ará ìwó ń bọ̀ wá kan ara Ẹdẹ. |
| Àsọtọ́ àti àkọtọ́: | Oyè tó kan ará Awó ń bọ̀ wá kan ara Ẹdẹ. |

Ìlú Ìwó jìnnà sí ìlú Ẹdẹ, ṣùgbọ́n ìlú Awó jẹ́ ìlú oníbejì pẹ̀lú Ẹdẹ, wọn tí wọnú ara wọn. àwọn ìlú méjéèjì yìí ní wọ́n dì jọ wà ní abẹ́ ètò ìṣejọba ìbílẹ̀ Ẹgbẹ́dọ̀rẹ́ ní ìlú Ọṣun. Bí wọ́n bá pín nǹkan fún ìlú Awó, ó di dandan kí ìlú Ẹdẹ náà gba tirẹ̀. Èyí ló wá bí òwe òkè yìí pé tí nǹkan kan bá kan ara Awó kí ara Ẹdẹ náà má fòyà, ó ń bọ̀ wá kan òun náà. Sùúrù àti ìfaradà ní wọ́n máa ń fi orí òwe yìí sọ àti pé wọ́n a fi gbani ní ìmọ̀ràn láti ní ìrètí pé kò sí ẹni tí Ọlọ́run kò ní ṣe fún.

| | |
|---|---|
| Àṣìpa òwe: | Ọmọ ọsàn ní í kó pónpó bá ìyá rẹ̀. |
| Àsọtọ́ àti àkọtọ́: | Ọmọ oṣè ní í kó pónpó bá ìyá rẹ̀. |

Oṣè jẹ́ igi ńlá, tí ó sì máa ń ga, kò rọrùn fún ẹ̀dá ènìyàn láti gun igi oṣè rárá. Igi ọsàn jẹ́ igi tí o máa ń so èèso ẹlẹ́rìn-dòdò, igi ọsàn kì í ga púpọ̀ àti wí pé kò sí ọ̀nà tí a kò lè gbà láti ká ọsàn. A lè lo akọ́rọ́ tàbí kí a tún lo ọ̀nà mìíràn tó rọrùn. Pónpó tàbí kùmọ̀ jẹ́ igi kúkúrú tí a gé lọ́nà tí a fi lè jù ú bá nǹkan. A kò lè lo pónpó tàbí kùmọ̀ láti fi ká ọsàn nítorí pé tí a bá ṣe èyí, ó lè jẹ́ ìṣòro fún wa láti rí ọsàn náà mu, nínú kí pónpó tàbí kùmọ̀ ba ọsàn náà jẹ́. Bí a bá fẹ́ ka èèso oṣè, a kò lè gun igi yìí dípò bẹ́ ẹ̀ kùmọ̀ tàbí pónpó ni a máa lò láti fi ka èèṣo yìí. Gbogbo ìgbà tí a

bá ń ju kùmọ̀ tàbí póńpó yìí ni igi ọṣè a máa fara kááṣá jíjù tí à ń ju póńpó bá à. Ọṣè tí a fẹ́ ká yìí ló ń kó ìyà jẹ igi ọṣè.

Nígbà tí a bá fẹ lo òwe yìí, á jẹ àsìkò tí alásùnmọ́-ọ́n ẹni bá ta ẹrẹ̀ sí ènìyàn lára, nípa ìwà ìbàjẹ́ tó hù sí ẹni tí o ń fi ọ̀rọ̀ ìbànùjẹ́ gún ènìyàn lára ṣùgbọ́n tí a kò ní ọ̀nà mìíràn ju kí a gba àbùkù yìí mọ́ra lọ.

## Ọ̀nà Àbáyọ Fún Àyọrísí Rere Àṣìpa Òwe

Bí Ọlọ́run bá pá ènìyàn lórí, a máa fi irun àyà di. Bí o tilẹ̀ jẹ́ wí pé àsọtọ́ àti àkọtọ́ ló ṣe àkóbá fún àṣìpa òwe Yorùbá, àwọn ìlànà kan wà tí a lè ṣe àmúlò rẹ̀ láti lè fi jẹ́ kí àtúnṣe wáyé lórí àwọn òwe tó ti doríkodò bí àdán wọ̀nyí kí a fi lè dẹ́kun ìpèdè àìtọ́ láwùjọ.

Àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá gbọ́dọ̀ gbájúmọ́ kíkọ́ ẹ̀kọ́ tó rinlẹ̀ lórí àsọtọ́ nítorí pé àsọtọ́ tó mẹ́hẹ ni àkọtọ́ ọ̀rọ̀ fi ń wáyé. Bí àpẹẹrẹ, nínú òwe 'Danwò ló bí ìyà ọ̀kẹ́rẹ́" ó ṣe é ṣe kí ó jẹ́ wí pé àkọ̀tọ́ ló mẹ́hẹ lórí fífi àmì ohùn sórí "Ìyà" ló di "Ìyá" ni wọ́n fi ń sọ pé 'dánwò ló bí ìyá ọ̀kẹ́rẹ́'.

Ká gbìyànjú láti máa ṣe àmúlò èdè Yorùbá nínú ilé ẹni kọ̀ọ̀kan wa ìdí ni wí pé ẹlẹ́rù ní yóò gbé nǹkan rẹ̀, tí onígbá bá sì pe igbá rẹ̀ ni àkúfọ́, ọmọ aráyé a bá a fi kó ìdọ̀tí. Kí a má jẹ́ kí ìbáṣepọ̀ tó wà ní aàrin wa pẹ̀lú àwọn édè mìíràn ṣàkóbá fún èdè abínibí wa tí a mọ̀ sí Yorùbá.

Bákan náà ni kí àwọn ìjọba, pàápàá jùlọ àwọn ẹ̀ka alábójútó ètò ẹ̀kọ́ kí wọn gbìyànjú láti sọ ọ́ d'òfiin fún gbogbo ilé ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, girama àti ilé ẹ̀kọ́ gíga láti máa ṣe àmúlò èdè abínibí bí ó ṣe tọ́ àti bí ó ṣe yẹ kí àṣìpá òwe àti àwọn aṣọsódì lè d'ohun ìgbàgbé ní àwùjọ wa.

Ọ̀nà mìíràn tún ni pé kí àwọn òbí máa gbìyànjú láti máa pa òwe bí ó ṣe tọ́ fún àwọn ọmọ nílé nígbà tí wọ́n bá ń fi ọ̀rọ̀ jomitoro ọ̀rọ̀. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn akọ̀ròyìn tàbí akaròyìn nípa ṣíṣe àmúlò òwe bó ṣe yẹ.

Lákòótán, kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ nípa ìwádìí múra láti ṣe ìlànà kíkọ́ èdè Yorùbá lórí afẹ́fẹ́ pẹ̀lú ìmọ̀ ẹ̀rọ ayélujára.

## Àgbálọgbábọ̀

Òwe jẹ́ ọ̀kan lára ewì arángbọ̀ èdè Yorùbá, èyí tí ó ṣe wí pé a kò lè sọ̀rọ̀ láì pa òwe kan tàbí méjì ní àwùjọ Yorùbá, bí aṣafọ̀ kò bá jingíri nínú ṣíṣe àmúlò òwe irúfẹ́ afọ̀ bẹ́ẹ̀ kò kún tó, àṣìpa òwe tí wá fẹ́ d'àṣà mọ́ wa lọ́wọ́ nítorí àìlákàkún ìtọ́jú èdè abínibí wa. Àyọrísí iṣẹ́ yìí fi hàn pé a tí ń dorí òwe kodò láwùjọ, tí a kò sì wẹ̀yìn wò bóyá ó tọ́ tàbí kò tọ́. Ó jẹ́ ohun ìyàlẹ́nu pé àwọn àgbàlagbà náà tún ń si òwe pa látorí ìwà ọ̀làjú àti gbígbé èdè àjòjì ga lórí èdè Yorùbá. Àbájáde èyí ni ìdójútì fún ọmọ Yorùbá tí kò lè pa òwe bó ṣe tọ́ àti bó ṣe yẹ mọ́. Àlàkalẹ̀ àwọn àbá wa ni pé kí àwọn olùkọ́ gbìyànjú lórí titẹpẹlẹ mọ́ ìlànà àsọtọ́, àkọtọ́, ṣíṣe àmúlò èdè nínú ilé, láàárín àwọn òbí sí ọmọ pàápàá jùlọ pípòwe bó ṣe tọ́. Bákan náà kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lórí iṣẹ́ ìwádìí nípa kíkọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá lórí àwọn ẹ̀rọ gbogbo.

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adégbìtẹ́, A (2003) Proverb and Conflicts among Yorùbá popular musician." Nigeria Music Review. No 4, 25-32.

Adéoyè C.L. (1979). Àṣà àti Ìṣe Yorùbá. Ìbàdàn: Oxford University Press.

Adéyẹmí L. (2006). Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá. Ìjẹ̀bú-Òde: Ṣhebotimọ Publications.

Ajíbọ́lá, J.O (1979). Òwe Yorùbá. Ìbàdàn: University Press Ltd.

Fájẹnyọ̀, A àti Adéoyè, A. (2016). Ipa Òwe Nínú ìfẹṣẹ̀múlẹ̀ Ìwà Ọmọlúàbí Láwùjọ Yorùbá nínú Ìrìnàjò Ọgọ́rùn-ún ọdún orílẹ̀ Èdè" Nàìjíríà nínú Ìtànsán Oòduà: Jọ́nà Ẹgbẹ́ Olùkọ́ Èdè Yorùbá Kọ́lẹ́jì Ẹ́ńsìì, fólúùmù 5, nọ́ḿbà 1. P.1.

Fátùrótì, O.R. (2015) "Ìlò Òwe Nínú Àṣàyàn Ewì. Adébáyọ̀ Fálétí nínú LÁÀŃGBÁṢÀ: Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá, University of Lagos. No 19, pp 55-70.

Kòṣéémánìí, S. (2010) Òwe Lẹṣin Ọ̀rọ̀. Ìbàdàn: Yew Books.

Ládélé, T.A (ay). (2006). Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá. Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.

Nwankwo, C àti Odokara, B. (2012). Proveb use in the age of media technology: A case sustain and propagate Igbo Proverbs. OJOLA: Obudu Journal of Languages. Vol 12(1) pp 1-9.

Ọlákòlú, O.T. (2006). Ìṣòro tó ń dojúkọ Àkọtọ́ Èdè Yorùbá. Nínú Ìtànsán Oòduà, Jọ́nà Ẹgbẹ́ Olùkọ́ Èdè Yorùbá kọ́lẹ̀jì Ẹ́nsìì, Fọlóhùn 5, Nọ́ḿbà 1. Pg 61.

Ọpẹ́fèyítìmí, A. (2011). Tíọ́rì àti Ìsọwọ́lo-Èdè. Ifẹ̀: The Department of Linguistics and African Languages, Ọbafẹ́mi Awolọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Owómóyèlá, O. (2005). Yorùbá Proverbs. Lincoln & London: University of Nebraska Press.